

# MÁMÁ, KÍ LÓ DÉ TÍ O FI Ń ṢE
# WÀHÁLÀ?

## Tí o bá ní àwọn ìdọ̀tí láti oko tàbí ilé ìdáná, kí o tó sun wọ́n tàbí kí o sọ wọ́n nù, o lè...



Yí wọ́n padà sí Biochar láti mú ilẹ̀ oko rẹ dára sí i tàbí kí o tà á.



Yí wọ́n padà sí Briquette láti lò ó gẹ́gẹ́ bí èédú tó kì í mú èéfín púpọ̀, tó sì máa ń jó dáadáa.



Yí wọ́n padà sí Compost láti lò ó gẹ́gẹ́ bí ajílẹ̀ àdánidá (organic fertilizer) fún oko rẹ.

## Ìdí Tó Fi Dára Láti Yí Ìdọ̀tí Rẹ Padà Sí Ohun Tó Wúlò

- Ó máa ń dín èéfín àti ìdọ̀tí afẹ́fẹ́ kù.
- Bí o ṣe ń jẹ́ kí ayíká rẹ mọ́, ó tún máa ń dín eṣinṣin, eku àti àwọn kòkòrò tó ń fa àìsàn kù.
- Olè rí owó àfikún nípa títà Biochar, Briquette tàbí Compost.
- Briquette jẹ́ epo ìdáná tó dára, ó sì máa ń gba ọ̀ là kúrò nínú wàhálà wíwá igi ìdáná.
- Compost máa ń mú kí irè oko pọ̀ sí i.
- Èéfín tó dín kù túmọ̀ sí ìlera tó dára fún àwọn obìnrin àti àwọn ọmọ.

"Ẹ jẹ́ ká fọwọ́ sowọ́ pọ̀ láti yí ìdọ̀tí wa padà sí ọrọ̀, kí a sì mú ayíká wa dára sí i."

greenfuturewomen.org

Ó wà ní Abeokuta, Ijebu-Ode àti Odeda, ní Ìpínlẹ̀ Ogun.

ecobriquette.org